**STRONG TOWER ACADEMY.**

**IṢẸ́: YORÙBÁ NOTE**

**OLÙKỌ́: AYA ÀJÀYÍ.**

**KÍLÁSÌ: J.S.S. 2**

**Ọ̀SẸ̀-KẸ́RIN (4th Wk)**

KÓKÓ-IṢẸ́: Àpólà ọ̀rọ̀-ìṣe. (Verb Phrase)

Àpóla ọ̀rọ̀-ìṣe ni kókó gbólóhùn nínú èdè Yorùbá. Ó máa ń sọ ohun ti olùwà ṣe. B.A

Múrí **<u>lọ</u>** si Ile-Ifẹ̀

Kọ́lá **<u>sáré</u>**

Bọ́lá **<u>rẹ̀rìn-in</u>**

**<u>Àbùdá Àpóla ọ̀rọ̀-ìṣe.</u>**

1. Àpólà ọ̀rọ̀-ìṣe le ṣiṣẹ́ bíi odindi gbólóhùn kí ó si gbé ohun tí a fẹ́ jáde. (single verb)

B.A: Wa, jáde, jokoo, dìde, sáré.

2. Àpóla ọ̀rọ̀-ìṣe lè jẹ́ ọ̀rọ̀-ìṣe àti àbọ̀, (verb + Object)

B.A. **Àpola Ọ̀rọ̀-Iṣe.**

| **Ọ̀rọ-Iṣe (verb)** | **Àbọ̀ (Object)** |
|---|---|
| **Ra** | **àmàlà** |
| **Mu** | **omi** |
| Se | ounjẹ |
| Pa | ẹran |

3. Àpólà ọ̀rọ̀-ìṣe lè jẹ́ aṣèrànwọ́ ọ̀rọ̀-ìṣe, ọ̀rọ̀-ìṣe àti àbọ̀. (Preverb, verb, object).

B.A Àpóla Ọ̀rọ̀-ìṣe.

| **Aṣèrànwọ́ ọ̀rọ̀-ìṣe (preverb)** | **Ọrọ-iṣe(verb)** | **Àbọ̀(object)** |
|---|---|---|
| ṣẹ̀ṣẹ̀ | yege | idanwo |
| mọ̀ọ́mọ̀ | fọ́ | àwo |
| tètè | sáré | lọ |
| kúkú | gbọ́ | Yorùbá. |

4. Àpóla ọ̀rọ̀-iṣe lè jẹ́ ọ̀rọ̀-iṣe àti ọ̀rọ̀ àpọ́nlé. (verb + adverb)

B.A. Àpólà ọ̀rọ̀-iṣe.

| **Ọ̀rọ̀-iṣe (verb)** | **Ọ̀rọ̀ Apọ́nlé (adverb)** |
| --- | --- |
| Ga | fíofío |
| Pọ́n | wẹ̀ẹ̀ |
| Jẹun | yó. |

5. Àpóla ọ̀rọ̀-iṣe lè jẹ́ ọ̀rọ̀-iṣe àti ọ̀rọ̀ àpèjúwe.(verb + adjective)

B.A. Apóla ọ̀rọ̀-iṣe.

| **Ọ̀rọ̀-iṣe (verb)** | **Àbọ̀ (object)** | **Ẹ̀yán aṣàpèjuwè(adjective)** |
| --- | --- | --- |
| **Wọ** | **aṣọ** | **funfun** |
| Jẹ́ | ọmọ | rere |
| Pa | ẹran | ewúrẹ́. |

**IGBA: KEJÌ (2nd Period)**

**IṢẸ́: YORÙBÁ NOTE.**

**KÍLÁSÌ: J.s.s. 2**

**KÓKÓ-IṢẸ́: Bi àwọn Akọni Ẹ̀dá ṣe di Oriṣà Akúnlẹ̀bọ́(Deities: Former human beings)**

Ènìyàn ni ọ̀pọ̀ àwọn òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá ní ayé ijọ́hun. Wọ́n jẹ́ àkàndá ẹ̀dá ti ìṣe, iṣẹ́ , ìhùwá àti agbára wọn sọ wọ́n di ẹ̀dá ọ̀tọ̀. Àbùdá ọ̀tọ̀ tí wọn ni yìí ni o sọ́ wọ́n di àpésìn. Díẹ̀ nínú wọn ní ilẹ̀ Yorùbá nìwọ̀nyí:

Ṣàngó, Ògún, Ṣànpọ̀nná, Oriṣa-Oko, Ẹ̀ṣù, Morèmi. Abbl.

1. Ṣàngo. (God of Thunder and lightning). Òun ni wọ́n ń pe ní Olúfiran. Jẹ́ ọmọ Ọ̀ràmíyàn. O sì jẹ́ Ọba Aláàfin ní ilu Ọ̀yọ́ nígbà ayé rẹ̀. O ní agbára lorí àrá àti ìmọ̀nà-mọ́ná..

Oríkì Ṣàngó: Ṣàngó, olójú orógbó,

Ẹlẹ́ẹ̀kẹ́ Obì................

2. Ògún. (God of Iron)  Ògún jẹ oyè Ọṣìnmọlẹ̀ ní ilu Ile-Ifẹ̀ kí o to lọ sí ìlú Ìrè Èkiti níbi tí o ti yà bá wọn mu ẹmu nínú ilé Aró. Màrìwò ni aṣọ Ògún. Ẹ̀jẹ̀ ló ń mu, Ajá ni ẹran Ògun.Gbogbo ohun to bá jẹ́ irin jẹ́ ti Ògun. Ìdi nìyí tó fi jẹ́ pé àwọn Àgbẹ̀, àgbẹ̀dẹ, àti awakọ̀ sọ́ọ́ di òrìṣà ti wọ́n ń bọ.

3. Òrìṣà-Oko (God of fertility). Ògúnjẹ́miniyi ni orúkọ oriṣa – oko nígbà tí o wa ní ayé. O gbógun ti àwọn oṣó ati àjẹ́ ti wọn ń gbógun ti àwọn eniyan ilu, o si sọ agbára wọn di òfo. Nípa iṣẹ́ rere rẹ̀ o di oriṣa tí wọn n bọ títi di òní.

4. Ṣànpọ̀nná. (God of Smallpox) Ṣànpọ̀nná tí wọn n da pè ni 'bàbá àgbà, Ilẹ̀ gbóóná, olódè'. Dàgbà dé ibi pé igi ló fi ń rìn. Ṣànpọ̀nná ni àwọn Yorùbá gbà gbọ́ pé n fi àìsàn ìgbóná jà tí inú bá bí i. Ọbàtálá gba igi ọ̀wọ̀ rẹ̀. O  sì lée wọgbó. Inú igbó yìí ni wọ́n ti ń bọ́ tító di òní.

5. Èṣù (Devil}  Ìlú Ilé-Ifẹ̀ ní Eṣu kọ́kọ́ gbé nígbà ayé rẹ̀. Èṣù kọ́ iṣẹ́ ifá dídá lọ́dọ̀ Ọ̀rúnmìlà. Èṣù gbónu, gbóya, kò sẹ́ni tì kò lè kò lójú.Gbogbo ẹbọ to máa ń gbé ló máa ń fin. Èyí ló sọ ọ́ dí oriṣà tí wọn ń bọ.

5.  Morèmi (Brave woman) Ọmọ́rèmi jẹ́ ọmọ ìlú Ọ̀fà ní ìpínlẹ̀ Kwara, Ṣùgbọ́n ó fẹ́ ọkọ ní ilé-Ifẹ̀. O si jẹ akíkanjú obìnrin. Òun ní o gba àwọn Ifẹ̀ sílẹ̀ lọ́wọ́ ìkónilẹ́ru àwọn Ùgbò ní ayé àtijọ́. Nitori ọ̀rọ̀ ìlú, Mọremi fi ọmọ rẹ̀ kan ṣoṣo, Olúorogbo rúbọ fún odò ẹ̀sinminrin.. Nítorí iṣẹ́ ribiribi yìí, wọn sọ di oriṣa ní ìlú Ilé-Ifẹ̀.